Máa Gbàdúrà fún Ẹ̀mí Mímọ́

Torí Sámúsìnì bẹ Jèhófà pé kó fún òun lókun ló ṣe rí ẹ̀mí mímọ́ gbà. (Àwọn Onídàájọ́ 16:28)
Tí ìwọ náà bá gbàdúrà sí Jèhófà pé kí ẹ̀mí mímọ́ ràn ẹ́ lọ́wọ́, Jèhófà á dá ẹ lóhùn.

KA LÚÙKÙ 11:5-13. Jésù fẹ́ ká mọ̀ pé kò yẹ kó sú wa láti máa béèrè fún ẹ̀mí mímọ́, torí ẹ̀ ló ṣe sọ àwọn àpèjúwe mẹ́ta yìí: 1) ìṣù búrẹ́dì mẹ́ta (ẹsẹ 5-10); 2) ẹja àti ejò (ẹsẹ 11); àti 3) ẹyin àti àkekèé (ẹsẹ 12).

Kun àwọn àwòrán yìí, gé wọn jáde, kí ìwọ àti ọ̀rẹ́ rẹ kan tàbí ẹni kan nínú ìdílé yin wá ṣe ọ̀kan lára àwọn àpèjúwe Jésù tó wà ní Lúùkù 11:5-13 bí eré.

Fún àpèjúwe kọ̀ọ̀kan, béèrè pé:

- Tí ẹni kan bá sọ pé kí n fún òun ní búrẹ́dì, ẹja tàbí ẹyin, kí ni *èmi* máa fún un?
- Kí ni Jèhófà máa fún mi tí mo bá béèrè ẹ̀mí mímọ́ lọ́wọ́ rẹ̀?



www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania